**OWE**

Eni a mba na'ja ni a ma nwo loju a ki i feti si ariwo ọja.

# Irohin Yoruba

No. 755 NOVEMBER 25 — DECEMBER 1, 1959 Kobo Meji (2D.)

**LAKAYE ỌRỌ**

**OKELE** gbigbẹ, ti on ti alafia, o san ju ile ti o kun fun ẹran-pipa ti on ti ija lo.

**IBAWI** wo inu ologbon ju ogorun paṣan lo ninu aṣiwere.

# OLOYE AWOLỌWỌ NI O DAJU PE,

# ẸGBẸ OLOMI TI KUNA NINU IDIBO TI O MBỌ YI



OLOYE OBAFEMI AWOLOWO

DEWKIS-KUDU.

**NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi ni Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun sọ ninu ipade ipolowo idibo ti wọn ṣe ni Dewakis-Kudu pe, o ti daju-ṣaka nisisiyi pe, Ẹgbẹ Olomi (NPC) ti kuna patapata ninu idibo wọle Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ti nwọn yio ṣe ni ọjọ kejila oṣu ti o mbọ yi ki ọjọ ogun-idibo na to de... O ni, on ko si jẹ gba awọn mẹkunnu Ipinlẹ Ariwa ni imọran pe ki nwọn di ibo wọn fun Ẹgbẹ Olomi (NPC) ti ko fi igbakan ṣẹgun ninu iru idibo ti o tọna taara bayi ri.**

O si tun fi ibo ti o tọna-taara ti nwọn di ni Iha Ariwa Kameruu laipẹ yi ṣe apejuwe bi Ẹgbẹ Olomi (NPC) ti kuna patapata nibẹ. Eyi ni akọkọ ipade ipolowo idibo ti yio kọkọ ba sọrọ ni agbegbe Kano nigbati o fi Kabba silẹ larọ yi ati bẹrẹ ipolowo idibo ọjọ marun ni agbegbe yi. Oloye Awolọwọ sọ ni ilu na pe, idasilẹ eto pe, ẹniti o ba ti dagba ni eto a ti dibo ni o pa Ẹgbẹ Olomi (NPC) ku patapata.

## Ẹ MAṢE BẸRU, Ẹ DIBO FUN ỌPẸ

O si tun sọ fun wọn pe, lipa idasilẹ eto yi, yan ni iṣubu awọn Ẹgbẹ Olomi (NPC) fi daju-ṣaka bi igbati o ti daju-ṣaka pe, bi ilẹ ba ṣu, ilẹ tun nmọ ni, nitorina o yẹ ki gbogbo awọn ti yio ba dibo ṣe ọkan wọn giri, ki nwọn maṣe bẹru ni ile idibo, fun ihalẹ ati ibẹru pe boya Ẹgbẹ Olomi (NPC) yio da wọn sẹwọn, ki nwọn da ọkan le, ki nwọn si dibo fun Ẹgbẹ Afẹnifẹrt (Action Group) ni ọjọ idibo na.—Oloye Awolọwọ tun la a ye wọn pe, ni asiri ni nwọn yio di ibo na, ẹnikẹni ti o ba si kọ iwe ihalẹ kan sode lati fi ṣe ikilọ ntan ara rẹ jẹ lasan ni.

Oloye Awolọwọ si ṣe ileri fun wọn pe, gbogbo mẹkunnu Ipinlẹ Ariwa, ni yio bọ kuro ninu wahala ati ibanujẹ ti nwọn yio si bọ sinu alafia, ominira ati ara-lile bi Ẹgbẹ Afẹnifẹre ba bori ninu ibo na ti nwọn yio di ni ọjọ kejila oṣu ti o mbọ yi. Ipade nlanla mẹta pataki ni Oloye Awolọwọ ba wọn sọrọ ni ọjọ yi kanna. Nigbati o nsọrọ nipa ajumọṣepọ. O ni gbogbo awọn mẹkunnu ilu ni alajumọbaṣepọ awọn. O ni iyatọ ti o wa larin Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Ẹgbẹ Olomi (NPC) jinna ketekete sira won ju nkan ti o le pade lọ. Ti akọkọ (Ẹgbẹ Afẹnifẹre) dabi Ẹgbẹ Angẹli. Ti ekeji

(Wo oju ewe kerin)

## *Ijọba Ẹgba pa eto ile-wiwọn rẹ*

ABẸOKUTA.

NI aipẹ yi ni Aṣiwaju Ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ Egba, Ọmọ-ọba Adeniyi Adedamola ṣe ikede pe "Eto ile wiwọn fun eto owo-omi ko tun ni si mọ"

O si ṣe alaye pe awọn wulẹ da ọran yi ro funra ara wọn ni, ki iṣe nitori iro ti awọn Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ati Ẹgbẹ National Emancipation League yi mọ eto na lẹsẹ ni awọn ṣe pa eto ile wiwọn na rẹ.



Eyi ni apa kan diẹ ninu awọn ogunlọgọ ero ti o wa si ipade tt Oloye Awolọwọ ṣe ni aipẹ yi ni Sokoto

# IROHIN KAKIRI ILẸ YORUBA

## Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun bẹ Ado-Odo wo



Ọlọla John Rankine Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun ni o nfi ọwọ si iwe ibẹwo ile igbimọ Ado Igbessa lẹhin ti o ti ba awọn igbimọ na sọrọ tan ni Ado-Odo.

## Awọn Ijoye Ilesha kofẹ iwọsi pẹlu Ọwa

ILESHA.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ni awọn Ijoye Ilesa bi marundinladọta ṣe ipinnu kan pe ki Ijọba tete ba awọn ṣe ofin kan pe awọn Ẹgbẹ Oṣelu ko gbọdọ ṣe ipade ipolowo idibo larin ibiti ko jinna ju igba ẹsẹ bata si Afin Ọwa lọ. gbogbo awọn Ijoye na si sọ pe anu ṣe awọn pe, iwa arifin buruku gba a ni pe ki awọn ẹgbẹ oṣelu ma a fi igbagbogbo tanuba Ọba Alaiyeluwa Ogunmokun, Biladu Kẹta.

Alaga Ipade na ṣe ikilọ pe, afi bi Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ba tete ti ẹsẹ bọ ọran na ki nwọn si tete pana ọran na mọlẹ laiko jẹ bẹ ẹ, rogbodiyan le ṣelẹ ni ilu lairotẹle. Ọba Ọwa paapa si sọrọ ninu ipade na pe, suru enia a ma a dopin, ati pe ọran na ṣe nde aye ti o le fi tan on ni suru.

Awọn ọlọpa si wa lẹnu iwadi nipa iru ọrọ isokuso ti janduku enia kan sọ si Ọwa ninu agbo ipolowo idibo ti Ẹgbẹ Alakuko (NCNC) ṣe ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi, ati pe nwọn tun sọ aṣoju Igbimọ Ibilẹ kan lokuta, nitoriti o ti kuro ninu Ẹgbẹ Oṣelu wọn.

### Akande Balẹ ile Olukọtun ku

IWO.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu kẹwa ọdun yi ni Ọgbẹni Adewuyi Akande, Bale ile Olukọtun ku. Awọn ọmọ rẹ, Adelakun Ajani, Adekanmbi Akanji ati Aiyegbọ Abikẹ nawo-nara ni ibi oku na. Ologbe yi jẹ ọkan ninu awọn agbalagba ilu Iwo ti nwọn di onigbagbọ ni iwọn ọdun marun s'ẹhin. Lati igbana ni baba yi ti di pataki ninu jọ Ọlọrun. Ẹhin baba yio dara o.

***Ẹ ma a polowo ọja nyin sinu iwe "Irohin Yoruba"***




# MULTIVITE

TRADE MARK

**KORO EGBOGI IMARALE**
**FUN GBOGBO ẸBI**

Gbogbo ẹbi nilati mu Multivite nitoripe Multivite ni egbogi imarale "A" ninu eyiti yio ran wọn lọwọ lati le fi ara da awọn aisan bi otutu iba ati ayọkẹlẹ.

Koro egbogi Multivite tun ni:
Egbogi Imarale "B" eyiti o nṣe iranlọwọ lati ṣegun aarẹ ọpọlọori
Egbogi Imarale "C" ti o nran awọ-ara lọwọ lati mọ gaara, ki o si jọlọ, o si njẹki ehin fidimulẹ ki o si lagbara.
Egbogi Imarale "D" eyiti o nṣe iranlọwọ lati jẹki ẹsẹ awọn ọmọ-tuntun tọ si ọkankan ki o si lagbara.




BDH THE BRITISH DRUG HOUSES LTD. LONDON

Distributed by branches of THE UNITED AFRICA CO. OF NIGERIA LTD.



Ọkunrin yi ra Basikulu Raleigh kan— O nta ọja pupọ nisisiyi!

Basikulu Raleigh rẹ lo ngbe lọ Kiakia lati ọja de ọja O nko ẹru pupọ si, o nde ọdọ Ọpọlọpọ awọn onibara si, o si Njẹ ere pupọ si. O lọgbọn lo ṣe Ra Basikulu Raleigh.

RALEIGH

JẸ BASIKULU TI A FI OGEDE IRIN TUTU ṢE

Move with the times —ON A CYCLE

Bere nipa STURMEY ARCHER Ẹrọ ti o nmu kẹkẹ ologere rin pẹlu irọrun.

Ni ile iṣẹ ti a ti nto kẹkẹ to wa ni Mushin, ni Eko, ni a ti nṣe wọn pẹlu ọjulowo awọn ẹya kẹkẹ Raleigh



Eyi ni igbati Oloye Awolowo mba awon ara ilu Mallamfashi soro nigbati o nse ibewo kakiri agbegbe Sokoto





Ona ti o YA JULO lati "ṣegun" AIRIGBEYA

Oogun ti gbogbo aiye mọ pe o dara fun

INU-RINUN

Lo oogun "De Witt's Antacid Powder" lati da awọn irora ti o nfun e lẹhin onjẹ duro. O dara fun t'ọmọde t'agba.

Nigbagbogbo ni ki o ma a mu "DeWITT'S ANTACID TABLETS" dani


Ẹ dibo Fun Ọpẹ

# ỌRỌ AKEWI

Lati ọwọ Ọmọ-ọba Akibu Alarape, Ibadan

## IYA NI WURA

OLOTU ajinde-ara yio ma a jẹ nyin o. Ẹṣin ọrọ wa
toni fo-fẹ-rẹ-rẹ, o dori iya.

Nwọn ni iya ni wura, baba ni jigi ọmọ,
Ọjọ ti iya ọmọ ba ku ni wura nbajẹ.
Ọjọ ti baba ọmọ ba ku ni jigi ọmọ nwọmi.
Ngo ṣe bi iya ko le jọ'ya,
Ngo ṣe bi baba ko le jọ baba to bi ni lọmọ
Iya eni la ba fi gbogbo ọjọ aiye eni kẹ,
Ani bi olukaluku wa ba ti gbọ ti ẹlẹda wa tan,
Oriṣa akunlẹ bọ kan ko tun si mọ,
Iya eni l'oriṣa akunlẹbọ,
Iya ẹni ni alagborandun.

Pagidari, igida!
Iya to f'inu ṣ'oyun ẹni lọjọ gbọoro.
Pẹlu ọpọlọpọ aile ara,
Abajo! Aṣe, ọdẹ iba ro'ṣẹ, ọdẹ iba ro'ya
Ọdẹ iba pa ẹran tan iba ti f'ẹnikan l'ẹran jẹ
Melo la le ri ro l'ọran alabiamọ?
Ọjọ jijẹ ọkẹrẹ,
Ọjọ aijẹ ọkẹrẹ
Edumare lo mọ iye ọjọ t'ọkẹrẹ f'ebi sun laijẹun
Bẹ ẹ si ni, bi a ko ba ni fi gba kan bọ kan ninu
Ọjọ mẹta kan mbẹ, ti ko-ni-gbagbe titi aiye lọdọ
abiamọ
Bi i bẹ ẹ si ko, ẹnyin alabiyamọ, ẹ ja mi ni koro,
Ọjọ akọkọ ti ko nigbagbe lọdọ obirin,
Ọjọ na lọjọ idabẹ,
Ọjọ keji lọjọ ti nwọn mbere pe, iyawo ko yege bi o?
Ọjọ kẹta ti ko nigbagbe taiye yio fi raiye,
Ọjọ ohun na lọjọ nla ọjọ ikunlẹ abiamọ!

Pagidari, igida!
Ọjọ nla ọjọ ewu,
Ọjọ ibanujẹ, ọjọ ẹru-jẹjẹ
Ọjọ ẹkun ọjọ ẹrin,
Ọjọ bi-o ba-ti le ri- ari
Ọjọ ti ẹmi iya ọmọ mbẹ lagbedemeji ile aiye on ọrun
Ọjọ t'ẹkun pẹlu ayọ nsure alapantete da yara
alabiamọ
Bi baba ọmọ ti ngba oju ile wọle
Beni yio ma gbọna ẹburu jade.

(Wo oju ewe kẹfa)


Erukeru yowu ko le je

PALM LINE TI WA FUN IṢẸ NA

Yala a o fọ ko awọn ẹru ọja wa'le lati Ilu Oyinbo ni tabi lati lọ sibẹ ni, yala a awọn ẹru rẹ na gborin ni tabi kere ni nibiti o ti ngna ọja tẹlẹ ri ni tabi nibomiran ti o ṣe ajeji ni sa gbẹkẹle Palm Line. Awọn ọkọ titun, awọn oṣiṣẹ inu ọkọ ti o dara fun iṣẹ ti nwọn si ti ni oye nipa iṣowo Iwọ-Orun Afrika wa fun iṣẹ rẹ ni Palm Line!





Iṣẹ wa ni lati ma a ko gbogbo eru nyin

Ko o wa fun

PALM LINE

# IYA NI WURA

(Lati oju ewe karun)

Ti o ba buṣe gada, a doriko bi adan
O si digba ti a ba gbohun iya tan, ti a tun gbọ t'ọmọ
Ki gbogbo nkan to le fararọ.

Sibẹsibẹ na, iya ọmọ ko ni isimi
Orun ko si losan, orun kọ si loru,
K'ọmọ tuntun to parada lori itẹ, iya ti dide loju orun
Tani nje "aja" ni Mọsalasi?
Bi ilẹ ti ngmọ fẹrẹrẹ ni ida-ndaji,
Iya ọmọ ti gbomọ pọn sẹhin,
Bi o ti ntọju ọmọ ni o ndana onjẹ baba ọmọ
B'ọmọ ti nsunkun ọmu, bẹni omi oka ntiri lori aaro.
Baba ọmọ ko gbọdọ wọle laiba onjẹ nilẹ.
Ọmọ to nsunkun ọmu ko dakẹ
Orun a ti kantari ki iya ọmọ paaap to mukọ

NJẸ, ki iya ọmọ tun joko ki o bẹrẹsi mukọ,
Ọmọ tun nsunkun a ti yagbẹ.
Ẹkọ gbigbona di tutu k'ọmọ o to yagbẹ tan
Kaasa! ẹnyin enia wa, ẹ ko r'aiye lode?
Dakun, Edumare, ma jẹki abiamọ o padanu ọmọ
Ani, b'ọmọ ti ndagba diẹdiẹ,
Bẹni wahala iya rẹ tun npọ si !
Bi iya ọmọ ti ngbọna ẹburu wọle alalufara,
Bẹni yio ma a gba oju ile wọ ti Babalawo,
Iya ọmọ ko kọ lati d'ẹru olukọ,
Nitori k'ọmọ rẹ o le ba a mọwe,
Iya ọmọ ko kọ ki igba atẹ ilẹkẹ o di t'ọrunla
K'ọmọ rẹ o sa ti d'enia pataki.

Pagidari, igida!
Ibi t'a nwi la de yi o, ẹnyin ara ile,
Ẹnyin ero-alọ-ero-abọ, ẹ sure tete wa o,
Ẹ wa a woran ọmọ afibi-ṣolore,
Ani, ẹ wa a woran ọmọ ti o rijẹ loni tan, to gbagbe
iya rẹ
Afibi-ṣolore-ọmọ ti o nfi ojojumọ-aiye muti Oyinbo,
Iya nṣe agbe kiri ki o to ri epinni dakọ arọ mu,
Kini faari ọmọ ti o ngba owo gọbọi lẹnu iṣẹ Ọba,
Ti o gbagbe iya-olore atijọ-tijọ?

Ẹ wa a wo ẹsin ọmọ afibi-ṣolore,
Ojojumọ ni alailojuti npaṣọda bi ẹbọra,
Iya mbẹ nile ti o nfi aṣọ akisa bora
Alakọri ọmọ fi gbogbo aiye kọle kiri bi ẹiyẹ,
Iya mbẹ ni iyara lairi ọkan jẹ,
Alaimore ọmọ ntuwọjọ nijojumọ aiye,
O nfẹ lọ si Mẹkka, o nfẹ re'lu Oyinbo
O ti gbagbe iya to mbẹ nile lairi nkan jẹ
Kaasa! Ẹ dakun, bi alakọri ba mbẹ nitori ki o
jade wa o, akuku-u-bi, ọmọ-akoya.

Iya nṣamodi, nwọn ni bi o ba le ku, ki o ku
Iya ku tan, apoti ọti Oyinbo nkọlu ara wọn
Iya ti ko ri nkan jẹ loju aiye rẹ
Akuku-u-bi ọmọ ndana onjẹ kakiri adugbo,
Bi nwọn ti nṣe aisun ni nwọn nṣe ifa ọsan,
Okugbẹ ọmọ ko sun, ko jẹki nwọn o sun ladugbo,
Bi nwọn ti nṣe iranti ogoji ọjọ,
Bẹni nwọn yio ma a ṣe ti oṣu mẹta
Oponu ọmọ ti o ti ba oju iya rẹ jẹ
A-wi-taiwi, nwọn ni awọn ntun ẹhin iya awọn ṣe,
Yẹyẹ iṣẹ! Eepa npa ara rẹ, o ni on npa aja,
Awọn alakọri njegunmayan,
Nwọn ṣebi nkan rere ni awọn nṣe
Nwọn ti gbagbe wipe, "Gba-nṣu, ni gba lakaṣu"
O dọwọ onikaluku wa loni o, ẹnyin ara ile.

Ipe ti ọmọ ...aiye npe sinku lode toni,
Bi nwọn ba pejọ bẹ ẹ tọju olokunrun iba ye.
Gbogbo ọmọ ti ko ba fẹ ki iya on ma gbe on ṣepe
Lajule ọrun, o dọwọ nyin, ẹ maṣe gbagbe iya olore.
Gbogbo Eesu ti kaluku ba da fun iya rẹ loni,
ko si ẹniti ko ni ko tirẹ lọdọ ọmọ ni ọjọ miran ọjọ're
Ẹ ma gbagbe o,
Iya ẹni la ba ma a kẹ titi aiye,
Iya ẹni la ba ma a gbe gẹgẹ nigbakugba.
Iya ni wura baba ni jigi ọmọ.
Bi iya ẹni ba ti ku, ti baba ẹni ko si laiye mọ,
Ṣangba tifọ, ọlọran ti kun lọ bi oyin,
Dakun, Edumare, a bẹ ọ, Ọba-Adaniwaiye
Ẹlẹda wa pese fun wa kalẹ, ṣe itọju awọn to bi ni l'ọmọ
Ẹlẹda wa ma jẹki a jẹ alaimore, ọmọlangidi,
Ọmọ to ri jẹ, to rimu loni, to gbagbe iya,
Afaimọ ki o to ma pada di ẹniti o nṣagbe kio to jẹun
Bi bẹ ẹ sikọ, a jẹ wipe nṣe lo ronu piwada.

Abọ wa re e loni o, ẹnyin ara ile.
Olotu, a dupẹ o, o digba.



Aworan yi ni ti diẹ ninu awọn ara Bodinga ti o wa si ipade Ipolowo Ibo Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti nwọn ṣe ni ilu na. Oloye Awolọwọ ni o wa ni apa kan oke ti o nfi ọkọ ti nṣe ami idibo awọn Ẹgbẹ Olomi han awọn ipade na.




IGBIMỌ ILE KIKỌ

Igbimọ ti nkọle ni Ipinlẹ Iwọ Ọrun ti a da silẹ labẹ ofin kejila ti ọdun 1958 lati mà ṣe eto iṣẹ ọwọ ati itẹsiwaju ti bẹrẹ iṣẹ rẹ. Igbimọ yi ti ṣe eto ọdun meji fun iṣẹ itẹsiwaju ati ile kikọ eyiti a ti pese ọkẹ mẹtadinlogoji ati abọ pọun fun. Igbimọ yi yio kọ awọn ile ti o dara ti o si ni agbara lori ilẹ ti a ya, yio si ta wọn fun awọn enia; yio si ma ya awọn enia ti o ba tọsi lowo, ti nwọn ba fẹ kọ ile lori ilẹ ti wọn. Owo to ma pari ile yi yio bẹrẹ lati ẹgbẹrun de ẹgbẹdogun pọun nisiyi, ṣugbọn a le kọ ile ti owo rẹ ko to eyi ni ọjọ iwaju. A ti bẹrẹ ile kikọ ni Bodija ni ilu Ibadan, a si ti bẹrẹ si ṣiṣẹ lori ilẹ ti a ti yasọtọ fun eto yi ni Ikẹja. Ni Ikẹja Igbimọ yi nṣ'iṣẹ lori ile iṣẹ ọwọ ati ile gbigbe. Awọn enia le ri imọran gba lori ilẹ ati ile kikọ ni ile iṣẹ Igbimọ yi ni Ikẹja. A ṣe awọn eto yi fun anfani awọn enia ti ngbe Ipinlẹ Iwọ Ọrun nikan. Awọn enia le ri iwe alaye lori eto yi gba lọfẹ lati ọwọ awọn oga ile iṣẹ wọnyi:—

The General Manager,
Western Region Housing Corporation,
P.O. Box 867, Ibadan.

Officer in charge, Ikeja Branch Office, Western Region Housing Corporation,
Private Mail Bag No. 1016, Ikeja.

Offices of the Information Division, Ministry of Home Affairs and Midwest Affairs throughout the Region, Regional Library, New Court Road, Ibadan, and the British Council Library, New Court Road, Ibadan.

Ile Iṣẹ ti nkede Iṣẹ Ijọba Iwọ Ọrun Naijiria l'ó gbe ọrọ yi jade.

# ALAPARA IBADAN

ALAPARA—Ẹ ku owurọ, ẹo jire bi o?

OLOTU—Alafia ni a wa, a dupẹ lọwọ Ọlọrun

ALAPARA—Ọrọ mi arọ yi yatọ si eyiti mo ti mba nyin sọ tẹlẹ ri

OLOTU—Ṣe irohin Sariyu Rọtikatika na ni o fẹ tun sọ ni ọna miran?

ALAPARA—O ti o, ọrọ nipa iṣelu Naijiria ni, nitori aṣọ igba ni a nda fun igba, ninu igboke-gbodo mi, mo de ọdọ ọkunrin kan, ẹniti ẹnyin na mọ bi ẹni mọ owo ni, ṣugbọn orukọ enia ṣoro da panyanun bẹ ẹ, ki o ma ba a di ẹjọ, nko kuku mọ ofin



ẹnyin oniwe, nko si fẹ asọrọ-daran.

OLOTU—Ṣe ki iṣe pe o fẹ bu enia ni?

ALAPARA—O ti o, mo fẹ ṣe alaye ọrọ ti temi pẹlu rẹ sọ papọ ni.

OLOTU—Ohun ti a ko fẹ ni ebu, irọ ati ki a ma a pẹgan enia.

ALAPARA—gbogbo nkan ti ẹ wi yi gan ni emi na korira, nitoripe on ti enia ko ba nje ko yẹ ki o fi lọ ọmọ-nikeji rẹ.
Bi mo ti le pe ọkunrin ti mo ba pade na ni "Arijẹnimadaru". Lẹhin ti a ti ki ara wa tan ni o wa bi mi lere pe ninu Ẹgbẹ Oṣelu wo ni mo wa? Mo si da a lohun pe, awọn ẹgbẹ oṣelu ti o nfi ibẹru Ọlọrun ṣiṣẹ iṣelu ni emi ntẹle, nitori Ọlọrun ko fẹ irọ.

Emi na si tun bi i lere pe ninu ẹgbẹ oṣelu wo ni on na wa? O si da mi lohun pe ẹgbẹ oṣelu ti on ba le ma a gbale kiri ti on yio fi ma a ri owo ṣe ni on ngbale kiri nitori ọmọaraiye ko fẹ otitọ.

Lẹsẹkẹsẹ ti o ti sọ eyi ni mo ti mọ pe Arijẹnimadaru ni titorina ni mo ṣe pe e ni Arijẹnimadaru. Laisọ fun mi iru ẹgbẹ oṣelu ti o faramọ, mo ti mọ pe iru awọn enia bẹ ẹ ko ṣowọn ninu Ẹgbẹ Alakukọ. Mo wa sọ fun pe dajudaju Ẹgbẹ Alakukọ ni o faramọ. O ni kiniṣe ti mo fi mọ? Mo si fi ye e pe, ọrọ ẹnu rẹ ni o fi ọ han. O rẹrin titi o la omi loju.

Mo wa bi lere pe kini o tiṣe nri owo ṣe ninu Ẹgbẹ Alakuko? Oni "ṣe iwo paapa mọ pe ẹnu mi dun mo si mọ irọ pa, gẹgẹbi mo ti sọ fun ọ tẹlẹ pe "ọmọ araiye ko fẹ otitọ' o ranti pe ni akoko kan ti Ẹgbẹ Alakukọ bẹrẹ si rin irin-ajo kakiri ilu Naijiria ninu ọdun 1946, ti nwọn wipe nwọn nlọ gba Ijọba Ominira wa lati ilu Oyinbo, ti nwọn fi gba adoje pọnun (£13,000) jọ. Enia le sọ otitọ ko ri iru owo gọbọi bẹ ẹ gba jo lọwọ ara Naijiria?

Mo wa tun bi i lere pe kini Ẹgbẹ Alakukọ fi owo na ṣe? O ni "amọranbere pọ lọwọ ẹnyin Ẹgba, o ni ohun ti o ti mọ bi nwọn ti ṣe lọ, bi nwọn ti ṣe ti ija bọ ọ lọhun nipa bi nwọn ti ṣe fẹ nawo ni ọna irẹjẹ larin ara wọn ti nwọn si yọ ẹṣẹ si ara wọn ti nwọn fi pada bọ wa sile lẹyọ ni ọwọ ofo.

Mo wa tun bi i lere pe eelo ni owo ti iwọ ri ṣe ninu ikogun na? o si da mi lohun pe, on ko iti faramọ wọn nigbana on si wa ninu ero Ọlọrun ko fẹ irọ bi ti emi, o ni ṣugbọn nigbati nwọn de ti mo woye pe ao ri awọn kan ti nwọn yio bere owo na lọwọ wọn ti ko si si, ni mo wa ri i pe owo na di ajẹgun pata-pata ni yẹn ni mo ba bẹrẹ si ṣe gbaruku tẹle wọn.

Mo si tun bi i lere pe nṣe t'o wa nṣe gbaruku tẹle wọn yi kini o nri jẹ nibẹ. O ni mo nri onjẹ nibẹ, ti nko fi wa iṣẹ kan ṣe mọ. Mo si tun bi i lere pe ni ọna wo? O ni mo mọ ọpọlọpọ awọn janduku enia ti i ma a tẹle awọn lọ si ibi ipade ipolowo idibo, on si mọ ọna ti awọn ẹgbẹ le fi ba on wa onjẹ nipa kiko wọn jọ ati nipa sisọrọ didun si wọn leti.

ALAPARA—Aṣe e! ohun ti agbalagba fi njẹ ẹkọ wa ni abẹ ewe.

ALAPARA—Mo wa tun bi Arijẹnimadaru lere pe kini ṣe ti ọrọ kanṣoṣo ko fi si ni ẹnu awọn aṣiwaju Alakukọ

ARIJẸNIMADARU—Kini o ri to o?

ALAPARA—Ẹnu ọjọ mẹta yi ni Benson fi ẹnu fọ, ti nfi idi fọ, bi oloburo pe bi ilu Ologboni tilẹ di ilu oro, ohun ko ni ba Azikiwe ṣe nkankan papọ mọ. Ijọ kẹta ni o ti tun ko ọrọ na jẹ.

Bẹni Adeoye Adisa, Olori Ẹgbẹ Mabọlajẹ Ibadan tun halẹ tirẹ pe, Ẹgbẹ on ko ni ba Ẹgbẹ Alakukọ ṣ'ẹgbẹ mọ lailai. Asẹhinwa-asẹhinbọ, a gbọ pe o tun ko ọrọ rẹ jẹ, aja rẹ tun pada si ebi rẹ.

Mo ranti pe Olotu "Irohin Yoruba" ti sọ pe alasọkojẹ ni Ẹgbẹ Alakukọ, ọrọ wọn ko si ṣe tẹle, awon ẹgbẹ ti ko gba ara wọn gbọ, ti nwọn nfi inu meji ba ara wọn lo yio ti ṣe le ṣe Alakoso Ijọba Naijiria. Irọ npurọ fun irọ ni Ẹgbẹ Alakuko, ṣigidi ti ko ni ẹnu ti o wipe on nsọrọ.

Emi Alapara Ibadan nki nyin o di gba kan na o.




## IGBIMỌ IGBILẸ Ẹ ṢE PUPỌ

[illegible]

AKOLADE BANKOLE

### Ẹ la cyi ye mi ?

[illegible]

MOSES OYE AKANDE








Aworan isalẹ yi ni igbati Oloye Awolọwọ sọkalẹ ninu mọto ofurufu rẹ ni Mallamfashi








# IPADE IPOLOWO IDIBO ẸGBẸ AFẸNIFẸRE NI IPINLẸ ARIWA



Aworan yi ni ti awọn ogunlọgọ awọn enia ti o wa si ipade Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Funtua



Aworan oke yi ni igbati Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ba awọn enia sọrọ ni ipade ti nwọn ṣe ni Mallamfashi


FEDERAL ELECTIONS 1959

NOMINATION OF CANDIDATES

Attention is drawn to the fact that under the Electoral Regulations as amended CANDIDATES ONCE NOMINATED CANNOT WITHDRAW.

R. E. WRAITH
CHIEF ELECTORAL COMMISSION






Aworan yi ni igbati mọto ofurufu Oloye Awolọwọ fẹ gunlẹ ni Gusau




ESE wura wa ti oni yi ni eyiti a sọ ninu Timoteu Keji ori 2 ẹsẹ 19, bayi pe, 'Oluwa mọ awọn ti iṣe tirẹ'. Lati igbati Ọlọrun ti npaṣẹ fun awa araiye l ati ni igbagbọ ododo si On, ati iwa rere si ọmọnikeji wa, ni awọn elomiran ti gbagbọ, ṣugbọn titi di oni yi ni awọn miran ṣi nṣe ifẹ inu ara wọn, ti nwọn si nwipe ifẹ ti Ọlọrun ni awọn nṣe.

Ọpọlọpọ enia lo nrin gẹgẹ bi enia rere ati onigbagbọ ododo, ọpọ enia lo nwọ aṣọ gẹgẹ bi enia mimọ, ṣugbọn ti inu wọn buru ju ti eṣu lọ, ọpọlọpọ enia lo nsọrọ gẹgẹbi enia Ọlọrun, ṣugbọn ti nwọn jẹ oniṣẹ eṣu, ṣugbọn o daju pe "Oluwa mọ awọn ti iṣe tirẹ". Gbogbo awọn ti o ngbe inu afin ọba le ma a pe ara wọn ni ọmọ ọba, awọn ẹru ọba na le ma a pe ara wọn ni ọmọ ọba, ṣugbọn ọba mọ awọn ọmọ tirẹ toto, awọn ọmọ toto na si mọ ara wọn.

# BIBELI MIMỌ T'ỌRUN ỌWỌN IṢURA T'EMI

# "Oluwa mọ awọn ti iṣe tirẹ"

## Lati ọwọ Evangelist Akande, Ogbomọṣọ

Gbogbo awa onigbagbọ ti a npe ni Joseph, Jacob, Samuel, Deborah, ati bẹẹbẹ lọ, Oluwa lo mọ onigbagbọ ododo ninu wa, awa funra wa na si mọ ninu ara wa bi onigbagbọ ododo ni awa iṣe tabi bẹkọ. Bi awa ba iṣe ọmọ Ọlọrun nitotọ, emi yio ma a jẹ wa lẹri ninu ara wa, gẹgẹ bi ọrọ na ti sọ ninu Rom 8: 16, bayi pe, "Emi tikararẹ li o mba emi wa jẹri pe, ọmọ Ọlọrun li awa iṣe."



EVANGELIST AKANDE

* * *

Bi enia ba jẹ enia buburu ati oniṣẹ eṣu, ti awọn araiye ba si nwo o gẹgẹ bi enia rere, ẹri ọkan enia buburu na yio si ma a da a lẹbi, on paapa yio si mọ daju pe oniṣẹ buburu ni on iṣe, gẹgẹ bi otitọ ti a sọ ninu Isaiah ori 59, ẹsẹ 12, bayi pe, "Nitori irekọja wa npọ si i niwaju Rẹ, ẹsẹ wa njẹri gbe wa, nitori irekọja wa mbẹ lọdọ wa, niti aiṣedede wa, awa mọ wọn."

Ninu Johannu ori 16, ẹsẹ 10, ati ẹsẹ 66 titi de 71, a ri i pe ọpọlọpọ awọn enia ti o ju ẹgbẹdogbọn (5,000) lọ ni nwọn ntẹle Jesu Kristi, ti nwọn si njẹ akara, ti gbogbo wọn dabi onigbagbọ ododo, ṣugbọn "Oluwa mo awọn ti iṣe tirẹ". nikẹhin, awọn enia mejila pere lo ṣeku ninu wọn, ninu awọn mejila na, ẹnikan ninu wọn tun ya eṣu, nitorina ni Jesu Kristi fi sọ ninu Johanu 13: 18, bayi pe, "Ki iṣe gbogbo nyin ni mo nsọ, emi mọ awọn ti mo yan."

Bi o ti wu ki Ijọ awọn onigbagbọ kere tabi pọ to laiye yi, enia buburu bi Judasi Iskariot yio wa ninu wọn, awọn enia si le ma a wo iru enia buburu bẹ bi ẹnipe on gan an ni onigbagbọ ododo julọ, ṣugbọn ẹ maṣe gbagbe wipe "Oluwa mọ awọn ti ṣe tirẹ." Nigbati akoko na ba si to, Oluwa na yio yanju epo buburu kuro ninu alikama gẹgẹbi ọrọ na ti sọ ninu Malaki ori 3, ẹsẹ 18, bayi pe, "Nigbana li ẹnyin o yipada, ẹ o si mọ iyatọ larin olododo ati enibuburu, larin ẹniti nsin Ọlọrun ati ẹniti ko sin In".

Ọpọlọpọ awọn onigbagbọ miran ti di onigbagbe, ọpọlọpọ wọn si ti di ọmọ eṣu, ọpọlọpọ awọn ọmọ Imọlẹ ti di ọga ninu ẹgbẹ okunkun, sibẹ nwọn npe ara wọn ni onigbagbọ, wọn kun fun iṣẹ buburu gbogbo, sibẹ nwọn npe ara wọn ni enia mimọ, ṣugbọn inu mi dun pe, "Oluwa mọ awọn ti iṣe tirẹ."

Gbogbo ẹnyin ọmọ igbala, bi o ti wu ki o ri, ẹ maṣe fi ọna rere ati iṣẹ igbala na silẹ rara, ẹ maṣe tẹle ọna awọn enia buburu ti iṣe ọna iparun, bi awọn ọmọ eṣu ba ngberaga ti nwọn ba si npe ara wọn ni onigbagbọ ododo julọ, ẹ fi wọn silẹ, bi nwọn ba nyọ nyin lẹnu, ẹ ma a mu suru, ọjọ ifihan ati ẹsan fẹrẹ de ,ki ẹ si ma a ranti ọrọ ti Jesu Kristi sọ ninu Johanu 10: 14, bayi pe, "Emi ni oluṣọagutan rere, mo mọ awọn temi, awọn temi si mọ mi". Dajudaju, "Oluwa mọ awọn ti iṣe tirẹ".

# ORIN MIMỌ TI A FẸRAN

## Lati Ọwọ E. Alabi Thompson

SUGBỌN eyi ti ẹnyin ni, ẹ di i mu ṣinṣin titi emi o fi de. Ifihan 2 ẹsẹ 25.

1. Ha! ẹgbẹ mi ẹ w'asia  
Bi ti nfẹ lẹlẹ  
Ogun ranwọ sunmọ tosi  
A fẹrẹ ṣẹgun  
D'odi mu Emi fẹrẹ de  
Bẹni Jesu wi  
Ran 'dahun pada s'orun pe  
Awa o dimu

2. Wo ọpọ ogun ti mbọwa  
Eṣu nko wọn bọ  
Awọn alagbara ṣubu  
Li orukọ rẹ.  
D'odi mu Emi fẹrẹ de etc.

3. Wo asia Jesu ti nfẹ  
Gbọ ohun ipe  
A o ṣẹgun gbogbo ọta  
Li orukọ rẹ.  
D'odi mu Emi fẹrẹ de etc.

4. Ogun ngbona girigiri  
Iranwọ wa mbọ  
Balogun wa nbọwa tete  
Egbẹ tujuka.  
D'odi mu Emi fẹrẹ de etc.

**ITAN ORIN NA**

Igbesi aiye Onigbagbọ dabi ẹni ti o nlọ siwaju ogun, nitori igboke-gbodo ati ipaiya aiye yi. Igbogunti ninu ile, nibi iṣẹ ati lọna gbogbo.

Ṣugbọn sibẹsibẹ ẹnikẹni ti o ba gbẹkẹle Oluwa, ki yio padanu ohun ti o dara.


## CLASSIFIED ADVERTISEMENTS

### AKIYESI

KURANI Ọgọta Esu fun ariyanju ọrọ inu Kurani Ọgọta Esu ti a nṣe l'ede Larubawa ati Yoruba, eyiti o wulo fun Musulumi ati Onigbagbọ, tete fi owo asansilẹ £1. 15s. tirẹ ranṣẹ si ESAN KOGBOGUN SERVICE 8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria

Etu Funfun Omo owo

ASHTON & PARSONS

Wa fun ilera Omo re



Ti Ọmọ rẹ ba nke — Fun u ni Etu Funfun Ashton & Parsons — Yio si bu ẹrin




Fun Ọmọ ọwọ ni Etu Funfun ASHTON & PARSONS Ti ara rẹ ba gbona, ti ikun rẹ ko ba lelẹ, ti erigi rẹ ba ndun u nigbati ehin rẹ ba nṣẹ nọọ. Yio jẹ ki o sun, eyiti ara rẹ nfẹ fun ilera. Lọ ra Etu Funfun ọmọ ọwọ ASHTON & PARSONS nisisiyi. Ranti pe Etu Funfun omo ọwo ASHTON & PARSONS dara fun gbogbo ọmọde.

Etu Funfun Omo owo

ASHTON & PARSONS dara fun gbogbo idamu ehin omode

FUN WIWA MOTO PELU IRORUN




LO AWON EPO MOTO

ESSO

## Ijọba Ibilẹ Ibadan sofin lori owo-ifẹ obirin

IBADAN

LENULỌLỌYI ni Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ibadan ṣe ofin lori owo-ife obirin pe, ogbon ponun (£30) ni opin owo-ifẹ iyawo, nwọn si ṣe alaye iye bi nina owo na yio ti jẹ bayi pe:—owo-idana jẹ pọnun mẹwa (£10), owo-itoro jẹ pọnun meji-abọ (£2. 10s.), owo iya-gbọ-baba -gbọ jẹ pọnun mẹje abọ (£7. 10s.), owo aṣo iyawo jẹ pọnun meji abọ (£2. 10s.), owo isinku nile ana jẹ pọnun meji abọ (£2. 10s.), owo idana fun oye-jijẹ jẹ pọnun meji abọ (£2. 10s.) owo apo fun iyawo jẹ pọnun meji abọ (£2 10s.).

## Ajodun ikore Serafu Ogbomọṣhọ

EGBE Mimọ Kerubu ati Serafu Ogbomọsho yio ṣe ajọdun Ikore wọn ni olu-ibudo wọn ni Kiatika Ogbomọshọ ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kokandinlọgbọn oṣu yi ni agogo mẹwa owurọ. nwọn yio si ṣere aladun ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu kanna moju ọjọ Ikore na. Ẹni-owọ ti yio wasu Ikore na ni Evangelist J. J. Akinde. Awọn Ẹgbẹ Akọrin yio si kọ orin aladun.

# Awọn Akẹkọ-Agba Ika-Ejigbo ṣere ariya

IKA-EJIGBO

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi ni awọn akẹkọ-agba ilu Ika lẹba Ejigbo pagbo ere ariya nla kan ti nwọn si fi ilu, orin ati ijo ṣe ere ariya na fun gbogbo enia jake-jado agbegbe na. Awọn ero ti o wa woran ere na le ni irinwo (800) enia, to bẹ ẹ ti agbo-ere na fẹrẹ ma le gba wọn tan. Oloye Ogunlẹyẹ ni o kọkọ ba ijokọ awọn elere na sọrọ, ninu ọrọ rẹ, o kan-saara si awọn Alaṣẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun gidigidi fun iru anfani ẹkọ bayi ti nwọn pese fun awọn agbalagba.

Oloye Ogunlẹye si tun yin awọn olukọ fun ile-iwe-ọfẹ fun awọn agbalagba na, fun akitiyan wọn, awọn na ni awọn Ogẹni Oladunni, olukọ-agba, ati Adelakun, oluko fun awọn agba, o si tun fi ye gbogbo enia pe ko si ilọsiwaju ti ilu kan le ni laisi ẹkọ. Lẹhin ọrọ tirẹ ni Ọba Alayeluwa Oluka, Ika, tun ba gbogbo ijoko na sọrọ. O dupẹ lọwọ Ijọba Egbẹ Afẹnifẹre Ipinlẹ Iwọ-Orun fun kikasi ti o ka ilu awọn si ti o fun awọn ni anfani ẹkọ-ọfẹ fun awọn agba, o si ṣe adura pe ki Ọlọrun ran Ijọba na lọwọ ki nwọn le bori ninu idibo wọle Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ti o nbọ yi. O si fi han gbogbo enia pe ọgbọn enia ni o yege ninu awọn akẹkọ-agbalagba laipẹ yi.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu wọn enia jankan-jankan ti o wa si ibi ere ariya na ni awọn Ọgbẹni D A. Ogunlẹyẹ; S O Teru, I O Oyewọle, Fadeyi, Fagbemi, V A Aderonmu ati J O Idowu.

E ku aṣeyẹ o.

# Obirin kọraa fẹ kọ ọkọ silẹ

IKEJA.

LAIPE yi ni obirin Kọraa (Syrian woman) kan Iyaafin Violet George, ti o ngbe 21 Boyle Street l'Eko pe ọkọ rẹ Ọgbẹni Henry George, Olotu Ile-itaja Onjẹ "Bagatelle Hotel" l'Eko lẹjọ ikọsilẹ si Kotu Nla Ikẹja, o si mbere pe ki Kotu na ba on tu adehun igbeyawo ti awọn ti ṣe lati ọdun mẹsan sẹhin ka.

Ohun ti obirin Kọraa na pẹjọ le lori ni pe, ọkọ on, Ọgbẹni George roro pupọ si on o si nfi iya jẹ on. Ni ọjọ keje oṣu kini ọdun 1950 ni Ọgbẹni George ati Iyaafin rẹ na ṣe igbeyawo ninu Ṣọọsi Aguda Nla "Holy Cross Cathedral" l'Eko, nwọn si ti bi ọmọ meji fun ara wọn.

Esi ti ọkọ obirin na fi si ẹjọ ti o pe na ni pe, on ko roro si i rara, ṣugbọn iwa panṣaga paraku ni on paapa nhu. Ki Adajọ to yẹ gbigbo ẹjọ na sọjọ kẹtalelogun oṣu yi, o paṣẹ pe ki Ọgbẹni George kọ iwe ibere si iwe ẹbẹ ti Oloye M E R Okorodudu kọ fi toro aye fun obirin ti o pẹjọ na lati fi ba awọn ẹleri rẹ mejeji, ti ọkan ngbe ilu Itali ati ekeji ni ilu Ọba jiroro papọ lori ọran na.

## Ole fọle-fọle wẹwọn oṣu mẹsan

EKO.

LAIPE yi ni Adajọ Kotu Kekere kan l'Eko ju odaran ole kan, Adio Buraimọ, ti o ngbe 15, Ojubuku Street l'Eko si ẹwọn oṣu mẹsan nitoripe o jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ba a ṣe pe, o folẹkun wọ ile obirin kan ti o njẹ Salamọtu Shabi, o si ji iro aṣo kan ati gele kan ti owo rẹ jẹ pọnun kan ṣile mọkandilogun (£1 19s.) gbe nibẹ mọ obirin na lọwọ.

## Titilọpẹ ṣe ọjọ ibi rẹ

IBADAN.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni Iyaafin Comfort Ọlaoti Fatọla ṣ'ẹyẹ ọjọ-ibi fun Titilọpẹ ọmọ rẹ ti o di ọmọ ọdun kan, opọlọpọ awọn ọmọde at'agbalagba ni nwọn pesẹ ni ibi aṣeyẹ ọjọ-ibi na, iya ọmọ na si fi nkan jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lorun.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn ti nwọn wa si ibi ẹyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Adeniji, Oyeyinka, Orowale, Amosun, Makinde, Ọkẹ ati Iyaafin Oyeyinka.




# IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA

## Suberu Jato komọjade

AKWATIA-GHANA.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kini oṣu yi ni Suberu Jato okan ninu awọn ọmọ Ẹka Egbẹ Afẹnifẹre Ghana ṣe ikomo ọmọ ti Ọlọrun fi ta on ati iyawo rẹ Jaratu Atunwa lọrẹ. Nwọn si sọ oruko ọmọ na ni Abudu Yẹkini Bandele. Baba Egbẹ Afẹfẹre, Jinadu Akanji lati Kumasi, ẹgbọn baba ọmọ na nawo-nara. Orisirisi ilu ni nwọn fi ṣere nibẹ. Oba Akwatia, Kwance Donkor bọ si agbo o si jo ṣẹkẹrẹ.

Opọlọpọ awọn ọmọ Egbẹ Afẹnifẹre ni o wa lati Pramkese. Bi awọn enia ti pọ to bẹni baba ọmọ na si fi ijẹ ati mimu tẹ gbogbo won lọrun. Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaṣẹyẹ na ni Ogbẹni Kolawọle Bello, Sadiku Ajani, Iṣola Afolabi, Garuba Jinadu, John Akano, Alhaji Busari Ayinde ati awọn obirin bi Awawu, Adiatu Anike Moriamo Abẹgbe ati opọlọpọ ti ko si aye fun lati daruko.

Ki Oluwa fi ire kari o.

## Asiwaju Ẹgbẹ Ọlọmi kan wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre

KANO.

LAIPE yi ni Alhadji Jamilu Dantata, ọmọ ologbe Alhadji Alhasan Dantata, ti gbogbo enia mọ pe on ni o lowo-julo ni Naijiria ni igba aiye rẹ ti yọwọ-yẹse kuro ninu Ẹgbẹ Ọlọmi (NPC) o si wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group). Eyi ni o di igbakeji ti Alhadji Jamilu nfi ẹgbẹ na silẹ. Ninu iwe ifẹgbẹsilẹ ti Alhadji na kọ sọwọ si Ẹgbẹ Ọlọmi (NPC) o ni nigbati on fi ẹgbẹ na silẹ ni akoko, on lero wipe Ẹgbẹ Ọlọmi (NPC) yio tete ṣe eto Ijọba rere alanu fun gbogbo enia ni, ṣugbọn on ri i nisisiyi pe ẹgbẹ na tubọ nrẹhin pada si igba ti atijọ ni.

Alhadji Jamilu si tun fi eto Ẹgbẹ Ọlọmi (NPC) sun pe, nwọn nhu iwa-ipa si gbogbo enia, nwọn ko tilẹ bikita fun awọn talaka rara nwọn ko si ni anu wọn lọkan, awọn ti Ọlọrun ti gbega ni nwọn bikita fun. O si fi kun ọrọ rẹ pe, ẹgbẹ oṣelu kanṣoṣo na ti o ni anu gbogbo awọn mẹkunnu lọkan ni Naijiria ni Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group).

## Owolawi gbeyawo fun ọmọ rẹ

Asuokaw-Adeiso, Ghana.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi ni Ogbẹni Salawu Owolawi ṣe igbeyawo fun ọmọ rẹ Raifu Akande. Nigbati o ti ku ọjọ mẹta ni awọn ọrẹ baba oko-iyawo lati Kumasi ti de si ọdọ rẹ ti o si nfi jijẹ ati mimu tẹ wọn lọrun. Ẹgbọn oko-iyawo na paapa na wabi-wosi owo.

Orisirisi ilu ni nwọn fi da awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lara ya. Diẹ ninu awọn ti o wa si ibi igbeyawo na ni Alufa Raji Ilobu, Ogbẹni G. B. Igbaye, Shittu Alabẹrẹ, Alimi Ọladẹjọ, Salawu Adeyimika, Taimiyu Ọladapọ, Ọjẹ Onilu ati Iyaafin Jẹmi Arikẹ. Ọlọrun ki o ṣe iyawo ni abiyamọ o.

## Mọdarikan komọjade

OGUNI LẸBA MINNA.

NI ọjọ Eti ti iṣe ogbonjọ oṣu kẹwa ọdun yi ni Oluwa fi ọmọkunrin kan ta Ogbẹni Mustafa Mọdarikan ati iyawo rẹ Rafatu Monisọla lọrẹ, nwọn si ko ọmọ na jade ni ọjọ kejọ. Nwọn si sọ ọ ni Tajudeen Olayiwọla.

Baba ọmọ na si fi ijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun. Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn ti o wa si ibi ikomọjade na ni awọn Ogbẹni L. Erinfọlabi, Salawu Adepọju, Amusa Akintola, M B Adebayo, E F Wellington, M S Ọlarinoye, M Adebọtẹ Iyaafin Wosilatu Adukẹ, Salamotu Ejide, Amudatu Aṣabi ati Taibatu Adukẹ.

## Ọga Tesan Reluwe jẹbi esun owo-ehin

ZARIA.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi ni Adajọ Kotu Kekere ṣe idajọ wipe ki ọdaran kan Sulaiman Sanusi ẹni ọdun mejidilogoji, Ọga Tesan Reluwe (Station Master) Makdobi Zaria, ti o ti ṣiṣe fun ọdun mokanlelogun labẹ Reluwe fi ponun mẹdogbọn (£25) tanran si Kotu tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu meji nitori ti o jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun pe o gba ponun mẹta (£3) owo-ẹhin lọwọ oniṣowo malu ati obi kan, Malam Yamko larin oṣu kẹfa ọdun ti o kọja yi, ki o ba le fun un ni wangonu-ile-ẹru lati fi ko awọn ẹru rẹ.

## Awọn "aṣẹwo" mẹtala fi ponun marun-marun tanran si Kotu

EBUTE-METTA.

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹrindilogun oṣu yi ni Adajọ Kotu Kekere Ebute-Mẹtta ṣe idajọ fun awọn aṣẹwo-obirin mẹtala kan, Queen Kpononsen, Victoria Otu, Mariet Agba, Victoria **Idikom, Rebecca Samson,** Dellia Owa, Esther William, Gloria Eno, Akwu Allatey, Julliana Johnson, Adina Sokoto, Theresa Ajayi ati Esther Dawudu, pe ki ẹnikọkan wọn fi ponun marun marun (£5 each) tanran si Kotu tabi ki nwọn lọ si ẹwọn oṣu kookan nitoripe nwọn jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi wọn sun pe nwọn huwa aitọ, nwọn si npakọrọ kakiri Ile-itaja-onjẹ "Empire Hotel" ni Surulere, ni deede agogo mẹta oru ọjọ kẹdogun oṣu yi.







